# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU ( Apa 3 )

**Lati ọwọ J. O. Shoyinka**

Nibi ti mo ba ọrọ mi de lana niyi:—

Lẹkanna ni gbogbo nwọn dasẹ duro wai, Iroko wa bẹrẹsi sọrọ bayi:- Enia to, to, to, fun un l'osi nke titi ti o fi w'ọgbẹ. Aṣẹṣẹ w'aiye Ijimere ọwọ funfun lo mu lo aiye ọmọ araiye lo tọwọ rẹ b'epo, Iwọ ọmọ enia to farapamọ sinu igbo, oju ẹbọra ti to ọ, wi fun mi, tani le gba ẹmi rẹ la loni iwọ ọmọ enia.?



Aworan Oke yi ni ti Ilu Ajiran Awọn Oku

Ọsan gangan wa fun ọmọ enia lati fi rin kakiri, Oru wa fun awa alujannu lati fi rin kakiri, Iwọ ọmọ enia lo sọ wa di ẹni igbo, ẹni itanu, Iwọ ha tun ṣe ndi wa lọwọ? Emi yio kan ọ ni koru eemọ loni, mo mọ daju pe ak po arọni ni Iwọ iṣe, nibo ni Iwọ yio gba? O gbe loni.

Aiya Ogbojulogun ja to bẹ gẹ ẹ, ti ọgbọn ori rẹ fi parẹ, iye rẹ si ra bamubamu, ara rẹ si ti ku taitai bi iti igi, o pọfọ titi ko bọ si mọ. O ṣẹṣẹ wa ranti pe Ayunọrunbọ fun on ni Ado Idẹ kan lati ma lo ti idamu ba de.

Bi IWIN IROKO ti fẹ sọlu, kiakamọsa o ti fa ADO IDE ti Ayọrunbọ fu yọ laipẹ o ke li ohun rara pe Ayọrunbọ ! Ayọrunbọ ! ! oniko iku, ẹiye buburu ti je larin oru, idamu de o, gba wa o ! gba wa o ! ! ki o to sọ bayi tan, iji nla de gbogbo igbo daru, manamana nkọ yẹri, ara osan wa-wa-wa, ẹru ba awọn IWIN ti o fi je pe nṣe ni wọn nke pe Oro ! Oro ! ! Oro o ! ! !.

Gẹgẹbi ẹnyin papa ti mọ pe ẹbọra ko fẹ imọlẹ, bi Ayọrunbọ ti nbọ, bẹni Imọlẹ ntẹ le e pi ti o bẹ si lẹ nṣe ni ilẹ mọ kedere. O di bo lọ, yago fun mi, ni awọn IWIN fi salọ lọjọ na.

Nigbati ọkan Ogbojulogun balẹ tan, o dupẹ lọwọ Ayọrunbọ fun ẹmi wọn to gba silẹ. Bi o ti fa onde rẹ yọ ti o si fi na apata, didide ti awọn ẹgbọn rẹ ma dide Oniko iku ti parẹ mọ wọn loju. Awọn ẹgbọn rẹ si tun dupẹ lọwọ rẹ fun ẹmi wọn ti o gbala lọwọ awọn IWIN.

Lẹhin igbati wọn jẹun tan, wọn mu Irin ajo wọn pọn—Iṣoro akọkọ yi wa fi han wọn daju gbangba pe, Irin Ajo wọn nilati mu isoro wa pupọ.

Nigbati o di ọwọ irọlẹ ni wọn de LANGBASA ilu YEMỌJA, wọn ni lati tu wọn koja ninu ọkọ, Ojude Iya Alaro si ni wọn ni lati gba koja eyiti awọn kogbede npe ni (Mammy Water).

Nijirọlẹ, wọn de Langbasa ilu yẹmoja, omi lọ lọtun ati losi, o dudu rẹpẹtẹ bi aro, ko si ọna ti wọn le fi sọda odo yi a fi ti atukọ ba tu wọn koja, wọn joko leti doo, wọn nreti atukọ laipẹ ni ọkunrin gigun kan nwa ọkọ bọ wa si ọkankan ọdọ wọn ko to iṣẹju marun ti o ba gunlẹ, ohun ti o jẹ iyalẹnu ni pe Ọkunrin abami yi fi awọn bo oju rẹ, o duro leti bebe ọdọ, wọn ko si ba ẹnikan sọrọ rara.

Ki o to yẹhinpada. Ogbojulogun ti nkan ka lara o si ti bere lọwọ rẹ pe, njẹ o ha le tuwa joko odo bi? atuko na si dahun pe bẹni.

Ọkan ninu awọn Ọmọ Onilogbo bẹrẹsi gbọn, ẹru si nbaa, o fi ohun gbigbọn ba awọn ẹgbọn rẹ sọrọ pe, ẹnyin ẹgbọn mi nko le paṣẹ fun nyin.

Ṣugbọn mo le mu imọran wa siwaju nyin pe iba dara pupọ ti a ba sun nihin di ojumọ, ki atukọ miran lẹ tu wa, toripe ẹniti yio tu ni ti a ko ni ri oju rẹ ewu l'oko Longẹ ma ni ọrọ na o, ki a ma ba ṣegbe sinu alagbalugba omi yi, koi ti pari ọrọ rẹ tan, Ogbojulogun ti tari rẹ sinu ọkọ.

Atukọ nawo gan ọpa, ọkọ nlọ ya, ya, ya.

Nigbati orun wọ tan pata pata ni atukọ wa wọn de Ojude Iya Alaro, piri, ni ọkunrin abami yi si awọn lo ju, rẹ jọ t'ọmọ en a atidi rẹ dele jẹ ti ẹja. Awọn ọmọ Onilogbo bẹrẹsiwa riri wọn ko si mọ ati sa asala fun ẹmi wọn mọ, bi wọn ti tẹju mọọ, ti o ke bi ohun rara pe:-

Ẹ pa oju yin da alaye ki wo ẹbọra, ọjọ ti emi ba kọlu ina, ni ina nku, ọjọ ti igbin ba tẹnu bọ iyọ, iku a de ba a, emi ni s'ẹja s'enia, emi ni Oriko Iya Alaro enia bi nyin ni emi na, ohun ti o sọ mi da bayi, nko le fẹnu sọ, ṣugbọn mo fẹ ki ẹ mọ daju pe ọjọ oni ni Iya Alaro nṣọduu ohun ti ko ni jẹki ẹ di ẹran ogun loni nko ti iri i, a fi ti ẹ ba di atẹri, nitoripe ọmọ enia ni Iya Alaro fi rubọ, abọ mi re o ara ẹ ṣe giri, ọjọ nlọ, Ogbojulogun dahun pe, bi Obangiyi ba nle loke, ọwọ Iya alaro ko ni ka wa toripe ati igba iwaṣe ni ọwọ ọmọde ki ti ka igi oṣe, yio ma doyi ka ni. Ngo si fi han Iya alaro pe, Olorun nbẹ, enia na si nbẹ pẹlu.

Ṣeja si terin musẹn, ki Ogbojuleogun to pari ọrọ rẹ, yi igbi nla ti de, o ngbe ọkọ sihin, sọhun, igbokun ti ja danu, opa bọ lọwọ atikọ

Nibiyi ni ngo da ọrọ mi duro loni, ṣugbọn ki ẹ ma ṣe gbagbe pe, ngo un ma ba itan na lọ ni ọla

O daro o.

AT LAST THE WATCH WITH A PERSONAL TOUCH WITH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL

Réf. N° 55. PHOTO



PRICE £ 5.

WINDSOR

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹtadinlogun oṣu karun (17/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipapẹ lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o.

LATIFU BABALOLA
Akọwe Agb.

# IWE SI OLOTU

## Ondo Nfẹ Itọju Ijọba

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye lati kesi Ijọba Ibilẹ ẹkun Ondo ati paapajulọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lati ṣe ayẹwo ẹ ogbo awọn ọna to wọ ilu na. Mo si ro pe nwọn yio si ri pe ọpọlọpọ awọn ọna yi ni ko dara mọ bayi ati pe gẹgẹbi ojo ti ṣe nbẹrẹ bayi eleyi yio mu ki gbogbo ilu na bajẹ tan.

Mo si tun ri pe awọn alaṣe Ijọba Ibilẹ ilu Ondo si nfi ti ọrọ oṣelu si ọrọ bi ilu yio ṣe dara ati papa julọ ti awọn alakoso ijọba na ba tiri pe adugbo kan pe ẹgbẹ oṣelu to wa nibẹ ko fara mọ ẹgbẹ oṣelu to nṣe akoso Ijọba awọn ko ni gbiyanju lati ṣe itoju adugbo na ati papa nwọn yio si ma a gbiyanju lati fi pẹlu agbara mu awọn se ẹgbẹ ti nwọn ko fẹ.

Inu mi yio dun bi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ba le ṣe iwadi si eto akoso ijọba ibilẹ ilu Ondo mo dupẹ o, Olotu ajinde ara yio ma a jẹ ami

Emi ni
Olusọla Balogun
ONDO

## Awọn Ole Pọ Ni Tinubu

Mba sọpẹ bi Olotu ba le fun mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ alaka gbadun ti o si tun ntumo Yoruba fun wa yekekeke lati kesi awọn Ọlọpa ki nwọn ran wa lọwọ lati ba wa le ole to wa ni Tinubu

Ki a le mọ gba atẹgun ni asiko oru ni Ijoba sese fun wa awọn ole ibẹ ti pọju, bi enia ba gbagbe sun awọn ole yi yio bọ bata ẹwọ ṣẹlu

Inu mi yio pupọ bi awọn Ọlọpanu ba nlọ sibẹ lalẹ lati le ba wa le awọn ọlọṣa na kuro, nitoripe nwọn nba alafia ilu jẹ.

Ni aipẹyi alejo kan lo gbatẹgun nibẹ, were ni iṣẹju aya awọn ọlọsa yi ti ji ago ọwọ rẹ. nwọn tun bọ bata ẹsẹ rẹ, iwa yi ntabuku ilẹ wa asiko yi, ṣe ilẹ wa dun mọ awọn alejo

Emi ni
Tọlagbe
EKO

## Ẹ fun Wa Ni Idẹra

Inu mi yio dun bi Olotu bale gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ oloyin mọmọ ti o njade lojojumọ ti okun fun ogbọn ati oye lati kesi Ijọba Ibilẹ Ijẹbu-Ode paapa Ijọba Ibilẹ Iwọ-Orun ki nwọn le ba wa tun ilu Ijẹbu-Ode ṣe ati agbegbe rẹ bi Idọna Isade' Idomowo ati bẹbẹ lọ sibẹsibẹ alọ nia ri, a ko iti ri abọ rara, nigbati awọn aṣoju ninu ile- Igbimọ Aṣofin Ipilẹ Iwọ-Orun nsọ ọrọ yi fun wa, inu gbogbo wa lo si dun si pẹlu.

O si wa nkan ti nba wa lọkan jẹ pe, latigbati nwọn Otito ọjọ mẹta ti ati nreti omi-ẹrọ ati ina mọnamọna fun agbegbe Ijẹbu-Ode ṣe ileri yi fun wa. a ko tilẹ gbọ ọrọ na ju bẹlọ oju ati ẹniti o sọrọ ti o muṣẹ depo ẹniti o sọrọ ti ko le muṣẹ mọ.

Afẹ mọ nkan ti ẹfi Owo-Ori awọn b ba ṣe, a bi ẹ gba owoyi Idowu ẹsi nfun Alabi ni, oyẹ ki awa na ri nkan ti enfi owo ṣe, bi a ba ri ni ole wu wa lorr ti a osi le mọ fi itẹlọrun da owo ori na.

Mo dupẹ aye ti ẹgba Olotu

Emi ni
MOOKE
G. S. C. IJẸBU-ODE

## Ẹ ba wa bojuto eyi

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye lati ke si alakoso eto ẹkọ Ipinlẹ Iwọ orun lati yan awọn olu bẹwo si ọpọlọpọ awọn ile ẹkọ to wa lagbegbe oju omi Ọpọlọpọ awọn Olukọ to wa lagbegbe oju omi ni ki iṣẹ ẹ nwọn gẹgẹ bi iṣẹ ọpọlọpọ awọn omijanba oluko ti yio fi ile ẹkọ silẹ laikọ awọn ọmọ ile ẹkọ awọn Ijọba tọtori rẹ nfun lowo. Ṣugbọn ẹlomirin ninu awọn olukọ ni ko ni fi oju si ibi iṣẹ rẹ ti iko ni lọ si ile ẹkọ ti yio jẹ pe nwọn yio lọ ma pa ẹja pẹlu awọn ọmọ ile ẹkọ na.

Inu mi yio dun bi alakoso eto ẹkọ ba le tete mu oju to gbogbo iwa ti awọn janduku olukọ yi ma nhu nwọn yi. Modupẹ o olotu.

Emi ni
Aṣabi Oshilaja
ṢHAGAMU

## Ẹma Polo—wo Ọja Yin Sinu Iwe-Irohin Imọlẹ lojojumọ


## Congreves Female Remedy
(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹduda ara tabi aikoto ẹje lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun ara atinu wa ni o ma nfa oyi-oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, ẹfọri tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPENI:-

### Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọbi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi lwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji tabi aiperinyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio se iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi t o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ apo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọna-ọfun didun, ati orişirişi omiran pẹlu won mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)
ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba


## AKIYESI PATAKI!

Eyi ni lati kede fun awọn Onkawe IROHIN IMỌLẸ jakejado Ilẹ Naijiria pe ỌTẸLẸMUYẸ ti ajo de nişişiyi. Ọrọ re yio si ma a jade ninu IROHIN IMỌLẸ deede nişişiyi nitorina ki awọn onkawe wa mura silẹ lati ma a ka igilangọ ọrọ ỌTẸLẸMUYẸ ti yio ma jade ninu Iwe wa na

OLOTU


BI O BA NI
# Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe gbeyawo

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE
**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa we lẹẹkanşoşo ki o ri iyatọ*

# Alejo Kan Ku Si Ile – Iwosan

IKEJA :- O di pẹntuka ni ọjọ Ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni ile iwosan ti Ikeja nigbati Obinrin kan ti oruko rẹ njẹ Monilọla Adukẹ wa se abẹwo ọkan ninu awọn ẹbi rẹ ti o bimọ si ile ibimọ ile iwosan na.

O si to deede agogo meje abọ owurọ nigbati nkan wọnyi ṣẹlẹ ti obinrin na ba awọn alejo bi tire joko si ori ibi ijoko kan to wa ninu ile iwosan na, ni ojiji ni arabinrin na si ṣubu

Ọpọlọpọ awọn alejo na ti nwọn si jẹ obinrin bi ti Monilọla si ba ẹsẹ wọn sọrọ nigbati obinrin na si nkegbe fun iranlọwọ

Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn si gbe obinrin na lọ si ile iwosan ti awọn Dọkita ati awọn alabojuto obinrin si gbinyanju titi lati da ẹmi obinrin na si ṣugbọn obinrin na si ku,

Gẹgẹbi irohin to de ọwọ wa, nwọn ni nse ni Dọkita si nba iṣẹ lọ lara obinrin na, Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn si gbe oku obinrin na lọ si ile lakulaku fun ayẹwo.

Onirohin tun fi ye wa pe on bere gẹgẹ bi nkan na ṣe ṣẹlẹ oni awọn alakoso ile iṣẹ na ko sọ fun on ati pe nwọn si sọ fun un pe ṣebi o ti gbọ nipa rẹ ati ki iṣẹ oju onirohin wa ni nkan na ṣe ṣẹlẹ.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan. 20-Feb. 18) Alafia ara yio to ọ imọ yio si ba awọn gbajumọ kẹgbẹ pọ, maṣe ba ẹnikan sọrọ asiri papọ Ṣugbọn o le rin irin ajo ranpẹ kan ti ko jina loni.

PICSES (Feb 19-March 20) Nṣe ni gbogbo ara yio ma kan ọ, ti ailera yio di ọ ma, boju to ọrọ ara rẹ ki o si lọ kesi ọrẹ rẹ kan, ti o ti dele rẹ ti pẹ, Bi o ba mba obinrin ta, ki o maṣe jẹki o ko si ọ ni agbari,

ARIES (March 21-April 19) Iwọ yio ri irohin ti o runi loju kan gbọ. Iṣẹ yio pọ fun ọ lakoko yi, ṣugbọn iwọ yio ri iranlọwọ lati ọdọ awọn ijimi enia nwọn o si gbe ọ ga,

TAURUS April 20-May 20) Ohun to dara fun ọ ni wipe, ki o lo gbogbo ọjọ oni pẹlu olufẹ rẹ ọwọn, lati ibe ni irohin ayọ yio ti kan ọ lara.

GEMINI (May 21-June 21) Ọjọ ire li oni yio jẹ fun iwọ nibi iṣẹ rẹ ati fun awọn ẹbi rẹ. Ṣugbọn ohun ti o jẹ pataki fun ọ ni pe, ki o moju to alafia ara rẹ.

CANCER (June22,-July 22) Ara rẹ yio le nigbati o ba ti ba ọmọbinrin kan sere tan, lati ibẹ iwọ yio yangbajumọ kan ni ọrẹ. ọrọ ara rẹ kan tabi ti awọn ẹbi rẹ yio da ijọngbọ kan silẹ fun ọ

LEO (Junly 23-Aug 22) Kere ọjọ oni yio dara fun ọ iwọ yio ri owo fi logba, iwọ yio ri irohin aladun gbọ, bi o lọrọ pẹlu ọmọbinrin kan, fetisi imọran nipa rẹ, ki o si mu dani

VIRGO (Aug. 23 Sept.22) Iṣẹ ti o nse yio mu ifọkanbalẹ wa fun ọ, ṣugbọn ewu lojẹ fun ọ bi iwọ ko ba rora ma ṣe dẹdẹ.

LIBRA (Sept. 23-Oct 23) Irohin alayọ kan yio ṣẹlẹ, lati sakani ọdọ rẹ ati ire lọna kan. Ṣọra ki o maṣe ba ọga agba ja, ki o si ma ro ori wo ki o to sọrọ, nitori eyin olorọ.

SCORPIO (Oct. 24-Nov. 22) Ọpọlọpọ iṣoro ni iwọ yio bori ninu ọrọ ara rẹ, fi ifẹ han fun ẹniti o nifẹ rẹ lọkan, ki o si fa wọn mora,

SAGITTARIUS (Nov. 23-Dec 22) Iṣẹ pọ fun ọ loni, ṣugbọn ṣọra rẹ, nitoripe ko ṣe pe nitori iṣẹ pọ, ni gbogbo ọgbọn ori rẹ pare. Iwọ yio ba awọn gbajumọ ṣe ipade loni, nitorina ṣe pẹlẹpẹlẹ

CAPRICORN (Dec. 23-Jan. 19) Ọjọ oni miringindin fun ọ, ifẹ pataki yio gbilẹ larin iwọ ati awọn ọrẹ rẹ, iwọ o ri imọran atata kan gba, ki o si jẹ faaji lọ sode loni.


# Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun To Nbọ Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ

ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMONA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INA KUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa ọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWO NI ỌBA alagbara Olubori gbogbo ẹda patapata" Amin.

**WAS SAL M"**

AKIYESI: Gbogbo Musulumi Ododo lo ye ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA.
Iye Owo 5/6 £3 fun dọsini
MANAGER
N2/99 SHITTI STREET,
Ibadan



# Ẹ ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ṣe ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa da okun losan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara awọn iṣẹ tabi wehala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti koja Ọgbọn ọdun lọ si dedeadọrin tabi jubẹ lọ. Mo durẹ "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ rẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igbadun ati alafia yio de si ọ. Iyen daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:-
Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street, Lagos.

# Iwọ Ọmọ Enia Ronu!

Lati ọwọ DAVID CHARLES

Oferẹ jẹ ojojumọ ni gbogbo enia nṣe aroye nipa airi iṣẹ ṣe ati gbogbo idamu ti mbẹ ni ilẹ wa. Ara awọn ti nka iwe irohin ti ilẹ wa ati ti ilẹ okere ko si balẹ lati ma ri oniruru iṣẹle kakiri agbaiye Arakunrin ndide si arakunrin, ẹgbẹ ndide si ẹgbẹ orilẹ ede kan si nyan ekeji ni ipọsi

Ṣugbọn ninu gbogbo aibalẹ aiya yi, ohun kan so gbogbo wa pọ eyi ni pe a jẹ ẹda Ọlọrun. Awọn ọjọgbọn sọ wipe iriri wa ti oni kọ wa l'ọgbọn nipa ọna ti ao rin lọla. Bi iwọ ba faramọ ọrọ yi, kini ọgbọn ti iriri wọnyi nkọ ọ? Iru iwa woni? o fẹ ma ba lọ ni ọjọ iwaju

IFỌWỌSOWỌPỌ

Bi iriri aiyebaiye ba wọ inu ile aworan Ọlọrun ti nbẹ ninu ọkan wa, bakanna ni yio ran wa lọwọ lati mọ bi o ti nṣiṣẹ, lati ri kedere ohun ti o nfẹ ati ọna ti o ntọ.

Ọlọrun da aiye ko fi iyasọtọ sinu orisirisi orilẹ ede ẹya ati ede ṣugbọn oko gbogbo wọn jọ yika ohun kan. Bi o ba jẹ wipe gbogbo ilu ba ni ohun iṣura ilẹ ati iye enia kanna nigbana pinlẹ tabi orilẹ ede kan yio le ma dagbe lai faramọ ekeji. Ọlọrun ti ṣe eto ohun gbogbo ninu ile aiye tobẹ ti orilẹ ede kan fi nfẹ iranlọwọ ekeji ayafi ti o ba fẹ padanu ohun ti o ṣe pataki fun alafia ati ayọ rẹ.

Orilẹ ede kọkan jẹ orilẹ ed ti ayan lati wa iranlọwọ fun gbogbo ẹya yoku

Enia gẹgẹ bi ẹni kọkan jẹ ẹlẹgbẹ rẹ ni gbogbo ohun ti ko ni.

Ẹgbẹ kọkan ni oniruru enia pẹlu orisirisi agbara ati iwa Ẹgbẹ rere kan ko le ko akolupọ enia pẹlu ero kanna jọ. Agbara ati ilọsiwaju ẹgbẹ tabi ilu uri ori sun lati inu gbogbo iranlọwọ ti awọn enia ninu wa nipa aidọgba ile aiye, iwa ọgbọn ati ifẹ olukaluku ẹgbẹ tabi ilu kan ti o ba kun fun awọn elero kan ko le ni itẹsiwaju gẹgẹbi ẹgbẹ tabi ilu ti o ni orisirisi Dokita ṣugbọn ti ko ni agbẹjọro, oluko ati bẹ bẹ lọ.

ETO ỌLỌRUN

Larin oniruru enia ati orilẹ ede, Ọlọrun ni ṣamọna ile aiye rere pẹlu awọn nkan bi ohun iṣura ilẹ awọn enia ati bẹ bẹ lọ gẹgẹbi ohun elo. Ifẹ Ọlọrun si wa lori idagbasoke gbogbo awọn nkan wọnyi, ki ṣe ninu awọn enia kọọkan nikan.

Awọn ọna ọtọtọ marun ti a pin oju ilẹ aiye si ati aidọgba awọn onun ini inu ilẹ fihan pe Ọlọrun fẹ ifọwọsowọpọ ninu iṣẹ aje owo ati awọn nkan miran Ṣugbọn ọna ti aiye isisiyi ti awọn olowo miran fi nr gimi ohun ọrọ aiya fun ara wọn nikan ati fun ipinlẹ wọn ko ba ilana Ọlọrun mu

Eto lati fun awọn ẹya kan la bara lori ẹya miran, lati gba ominira ẹlomiran tabi lati ka awọn miran si ẹni itanu lodi si eto Ọlọrun. Awọn ilẹ Gẹẹsi ti kuna ri, ṣugbọn nisisiyi nwọn nsa ipa lati yi ilẹ ọba wọn si ti ajumọṣe (Commonwealth) yẹpere, ko si le ṣeeṣe pẹlu ọrọ enu

Fifi agbara tabi ominira fun awọn ti nbẹ labẹ ẹni le mu ifasẹhin wa fun alagbara; ṣugbọn ifẹ Ọlọrun ni.

Ọlọrun ti da aiye fun oniruru ẹgbẹ ti ngbe orisirisi ero jade Ẹni kọkan si nilati ni ominira lati ronu ni ọna ti o wu u.

Ijọba pẹlu ipa le ni agbara pupọ ṣugbọn ko le gbe ohun anfani jade.

Iru ijọba bayi yio ba iṣẹ anfani jẹ nipa fifi ipa mu awọn enia ilẹ rẹ foribalẹ fun u Dajudaju ijọba yi yio dibajẹ yio si kuna lati ṣe ohun ti o wu Ọlọrun.

Aṣa ẹnikọkan ni lati ka ara rẹ si ẹni mimọ ati lati ma tọka si aṣiṣe tabi iwa alebu ẹlẹgbẹ rẹ ki ṣe lọdọ enia nikan ni Iru aṣa yi wa, ṣugbọn o nṣẹlẹ larin awọn Ijọba ati ẹgbẹ.

RONU TOTO

Awọn orilẹ ede Iwọ-Orun aiye nyọ suti si awọn ti Ila-Orun bẹẹ gẹgẹ si ni awọn orilẹ ede Ila-Orun aiye nṣe si awọn na. Enia nja fun ara rẹ nikan lai bikita fun ẹnikeji rẹ. Bakanna ni iru iwa bayi nbẹ larin ilẹ wa ninu ile wa ni ibi iṣẹ wa ati ninu ẹgbẹ wa.

Gbogbo eyi nṣẹlẹ titi di oni oloni ṣugbọn ẹkọ kinni a ri kọ nibẹ iru iṣesi wa l'ọla? Njẹ awọn Ijọba wa ri ere kan jẹ ninu iru iwa bayi? O gba awa tikarawa bi? Bi idahun bajẹ bẹẹni a le ma lọ ninu iwa kanna. Ṣugbọn bi o bajẹ bẹẹkọ o si dani loju pe yio jẹ bẹ ki Ijọba enia ọmọde ati agba olowo ati mekuno mura lati ronu.

Ironupiwada tirẹ gẹgẹ bi ẹnikan tabi ti Ijọba le mu iyipada wa sinu ilẹ rẹ. Niwọn gbati o ba ti ka ara rẹ ati ẹnikeji rẹ si ẹda Ọlọrun ti o ko fi yatọ si iṣesi rẹ si awọn ẹya miran dajudaju ilu yio toro,

Ijọba wa ni aiye nipa aṣẹ Ọlọrun, ṣugbọn iṣẹ wọn ni lati dari ati lati tun ile aiye ṣe ki si ṣe lati lo ipa tabi lati doju ija kọ alakoso Kristi ko kọ wa bẹ, mo si mọ daju pe Mohammadu paapa lodi si iwa bẹ ẹ.

Nitorina Iwọ ọmọ enia ma duro de ọjọ ọla mura lati yipada ronu !

## AKIYESI PATAKI!

Eyi ni lati kede fun awọn Onkawe IROHIN tiMỌLẸ jakejado Ilẹ Naijiria pe ỌTẸLẸMUYẸ ti njo de nisisiyi. Ọrọ rẹ yio si ma a jade ninu IROHIN IMỌLẸ deede nisisiyi nitorina ki awọn onkawe wa mura silẹ lati ma a ka igilangọ ọrọ ỌTẸLẸMUYẸ ti yio ma jade ninu Iwe wa na

OLOTU

make it a successful
SEASON
with MERCEDES BENZ
TRUCKS

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.
LAGOS, APAPA & EBUTE METTA, IBADAN,
KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA,
PORT HARCOURT & ABA.

